# ỌNA TITUN ATI AAYÈ

## Heberu 10: 1-39.

### ẸKỌ 441 -- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: “Nitorina ẹ máṣe gbe igboiya nyin sọnu, eyiti o ni ère nla” (Heberu 10:35).**

A kọ ninu ẹkọ wa ti o kọja pe Ẹjẹ Jesu, ti a ta silẹ ni kalfari, ni a ti rọpo gbogbo ẹjẹ aÔ-malu ati ewurẹ ti wọn n ta silẹ ni gbogbo ọpọlọpọ ọdun nigba ti awọn Ọmọ Israẹli ṣI wa labẹ Ofin.

### Fifẹ ati Gbigbọran

Awọn irubọ wọnni ko mu inu Ọlọrun dun nitori pe awọn eniyan naa wa ninu ẹṣẹ sibẹ. Woli Isaiah kọwe si awọn Ọmọ Israẹli nigba kkan pe: “Oluwa ni, kini ọ̀pọlọpọ ẹbọ nyin jasi fun mi? emi kún fun ọrẹ sisun agbò, ati fun ọrá ẹran abọ́pa; bẹni emi ko si ni inu didùn si ẹjẹ akọ malũ, tabi si ti ọdọ-agutan, tabi si ti obúkọ” (Isaiah 1:11). O tun wi siwaju si i pe gbogbo apejọ ọwọ wọn (awọn̄ ti a ti ọwọ Ọlọrun ṣe ilana rẹ̀ tẹlẹ) jẹ irira si I, nitori ẹṣẹ ti o buru jai ti awọn eniyan naa n da. Ọlọrun paapaa sọ fun wọn pe: “ Bi ẹnyin ba fẹ́ ti ẹ si gbọran, ẹnyin o jẹ ire ilẹ na: ṣugbọn bi ẹnyin ba kọ̀, ti ẹ si ṣọ̀tẹ, a o fi idà run nyin: nitori ẹnu OLUWA li o ti wi i”(Isaiah 1: 19, 20). Ọlọrun ni inudidun si igbọran; aigbọran a maa mu ibinu Rẹ̀ wa.

Jesu fi han pe Oun jẹ Ọmọ pipe, nitori pe O ni ọkan lati ṣẹ O si n gbọran. O n fẹ lati ṣe ohun ti o wu Ọlọrun. Ifẹ ti o wa laarin Baba ati Ọmọ pọ to bẹẹ ti Jesu n fẹ lati ṣe ifẹ Baba Rẹ̀, bi o tilẹ jẹ pe eyi yoo mu un ṣe irubọ, nlá nlàni tita Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ lati ra awọn ẹlẹṣẹ pada. Ni ọna kan, ọ jiya fun ẹṣẹ gbogbo eniyan nigba ti O di Ọdọ-agutan Ọlọrun. Nitori pe o san gbese naa, aki yoo tun jiya mọ bi a ba ronupiwada awọn ẹṣẹ wa.

Ni ọpọlọpọ ọdun sẹhin ni awọn̄ woli ti kọ akọsilẹ pe Èsu yoo wa lati ṣe ifẹ Ọlọrun: Dafidi tilẹ kọ akọsilẹ ninu Orin Dafidi 40: 7,8, awọn ọrọ naa gan an ti Jesu tun sọ: “ Kiyesi i, Mo dé lati ṣe ifẹ rẹ, Ọlọrun” (Heberu 10:9). Ofin Ọlọrun jẹ idunnu Rẹ̀. Bi a ba fẹran Ọlọrun ni tootọ, awa pẹlu yoo ni inudidun lati ṣẹ ifẹ Rẹ̀.

Nigba gbogbo ni awọn Ju maa n wa ẹsun si Jesu lẹsẹ, wọn si kọ̀ lati gbagbọ pe, Ọmọ Ọlọrun ni Oun I ṣe. Nigba kan Jesu wi fun wọn pe: “ Ẹnyin nwá inu iwe-mimọ́ nitori ẹnyin ró pe ninu wọn li ẹnyin ni ìye ti kò nipẹkun; wọnyi si li awọn ti njẹri mi” (Johannu 5:39). Awọn Ju ka Iwe Mimọ, wọn si ro pe awọn ni iye ainipẹkun; ṣugbọn Jesu ni ki wọn tun wo o lẹẹkan si. Ninu Iwe Mimọ yi naa gan an ni a ti ṣe apejuwe Jesu. Wọn wi pe awọn gba Mose gbọ́, ṣugbọn Jesu wi pe, “Ẹnyin iba gbà Mose gbọ́, ẹnyin iba gba mi gbọ́: nitori o kọ iwe nipa ti emi” (Johannu 5:46). Ati ni akoko naa O wi pe, “Emi kò wá ifẹ ti emi tikarami, bikoṣe ifẹ ẹniti o rán mi” (Johannu 5:30). Nigba miran, O tun wi pe, “Emi nṣe ohun ti o wu U (Ọlọrun) nigbagbo”(Johannu 8:29).

Bi a ba fẹ lati dabi Jesu awa pẹlu yoo maa lepa lati wu Ọlọrun. Jesu wi pe: “Ẹnikẹni ti o ba nṣe ifẹ Baba mi ti mbẹ li ọrun, on na li arakunrin mi ati arabirin mi, ati iya mi” (Matteu 12:50).

A dan Jesu wo titi de gongo ninu Ọgba Getsemane, O si kigbe nibẹ pe, “Baba mi, bi ago yi kò ba le ré mi kọja bikoṣepe mo mu u, ifẹ tirẹ ni ki a ṣe” (Matteu 26:42) . Ifẹ Ọlọrun si ni pe ki O kú fun awọn̄ ẹlẹṣẹ -- bẹẹ ni Jesu kú, ati nipa iku Rẹ̀ O mu ifẹ Rẹ̀, tabi majẹmu Rẹ̀ ṣẹ.

### Majẹmu Titun

Nisinsinyi a ni Majẹmu Titun, tabi aṣẹ-ihagún titun. “O mu ti iṣaju kuro, ki o le fi did ekeji mulẹ” (Heberu 10:9). Nipasẹ aṣẹ-ihagún titun yi eyi ti Jesu fi idi rẹ̀ mulẹ nipa iku Rẹ̀ lẹẹkan titi lae, ki I ṣe pe a n gba wa la nikan ṣoṣo, ṣugbọn a n ṣo wa di mimọ pẹlu. Awọn alufa ni igba Majẹmu Laelae a maa ṣe irubọ lojoojumọ, ṣugbọn Jesu ṣe e lẹẹkan, bẹẹ ni a ko si tun ni I ta ẹjẹkẹjẹ silẹ mọ.

Lẹyin ti Jesu pari iṣẹ irapada Rẹ̀ tan, O jinde kuro ninu oku, lẹyin ti O si ti rin lori ilẹ aye yi fun ogoji ọjọ O pada lọ si Ọrun O si joko ni ọwọ ọtun Ọlọrun. O n duro de akoko Ipọnju Nla nigba ti yoo tun pada lati ran idajọ sori awọn eniyan aye yi ti wọn kọ lati sin In. A sọ asọtẹlẹ yi ni akoko Majẹmu Laelae.

### Idajọ Ọlọrun

A ṣe apejuwe idajọ Ọlọrun ninu Orin Dafidi 2 lọna ti o han gbangba. Onipsalmu wi pe awọn ọba aye n gbimọ pọ si Oluwa ati si Jesu, Ẹni oror Rẹ̀. “ Ẹniti o joko li ọrun yio rẹrin: Oluwa yio yọ ṣùti si wọn” (Orin Dafidi 2:4). Njẹ iwọ le ro o wo bi yoo ti buru jai to fun awọn ti o kọ aanu Ọlọrun, nigba ti o ba dide lati mi ilẹ aye ni ọna ti o

banilẹru lọpọlọpọ? Awọn isẹlẹ kekeke ti o ṣẹlẹ ni agbedemeji Ariwa si iwọ-oorun ilẹ Amerika ti mu ipaya nlá nlà ba awọn miran. Bawo ni yoo ti ri nigba ti awọṅ oke yoo ṣidi kuro ni ipo wọn ati ti awọṅ irawọ yoo si bẹrẹ si jabọ? Ati nigba ti Ọlọrun ba n rẹrin ibẹru wọn! Ọlọrun Baba t ṣẹ ileri fun Jesu pa akoko n bọ nigba ti Jesu yoo pa awọn ẹlẹṣẹ run: "Ọpá irin ni iwọ o fi fọ́ wọn; iwọ o si rún wọn wom-wom, bi ohun èlo amọ́" (Orin Dafidi 2:9). Gbogbo aye ni yoo wa labẹ akoso Jesu nigba naa bẹẹ ni gbogbo eniyan ti o wa laaye ni akoko naa ni yoo gbọran si aṣẹ Rẹ̀ yala wọn n fẹ tabi wọn ko fẹ. Gbogbo orilẹ-ede ni yoo jẹ "apoti-itisẹ" Rẹ̀ -- O le tẹ wọn mọlẹ bi ọ ba n fẹ bẹẹ.

**Ofin ninu Ọkan**

Ọlọrun ti ṣeleri pe " lẹhin na", lẹyin ti a ba ti jẹ awọn Ju niya ran, ti awọn diẹ ninu wọn ba si ti yipada si Jesu, ti a si ti gba ẹmi wọn la, Oun yoo kọ ofin Rẹ̀ sinu ọkan wọn. Eyi yi ni pe awọn eniyan wọnyi di atunbi gẹgẹ ba awati n di atunbi nisinsinyi nigba ti a jọwọ ọkan wa fun Oluwa. Nigba ti a ba gbadura titi a fi ni idaniloju pe a ti dari ẹṣẹ wa ji wa, A wẹ ẹṣẹ wa nu a ki yoo si tun ranti wọn si wa mọ. Ọlọrun a maa gbagbe ẹṣẹ ti a ba ronupiwada rẹ̀. Bi a ba fasẹhin ti a si tun dẹṣẹ, awọṅẹṣẹ wọnni yoo ran wa lọ sinu egbe ọrun apaadi ṣugbọn awọn ẹṣẹ ti a ba ti dari wọn ji ni lẹẹkan ti rekọja, a ti ri wọn sinu okun. Ṣugbọn Ọlọrun n beere pe ki a mu ọna wa ti o ti wọ tẹlẹ tọ ki a si ṣe ijẹwọ awọn ohun ti ko tọ ti a ti ṣẹ, bi ole, irọ ati fifi ọrọ banijẹ.

**Apejuwe**

Ninu ẹkọ ti a kọ nipa oriṣiriṣi ikele ti o wa ninu Agọ a kẹkọ pe agbala ajọ jẹ apẹẹrẹ iriri idalare --- tabi igbala. Ibi Mimọ si jjẹ apẹẹrẹ isọdimimọ. Nihin yi ni turari mimọ ti n jo lai dẹkun lori pẹpẹ wura,gẹgẹ bi adura ati iyin wa i ti maa lọ soke lai dẹkun lati inu ọkan wa nigba ti a ba ti sọ wa di mimọ́ ti a si di mimọ́. A fi aṣọ ikele kan bo Ibi Mimọ́ Julọ, eyi ni ni iyara kẹta, kuro loju gbogbo eniyan, afi olori alufa nikan, nibẹ ni Apoti Majẹmu gbe wa labẹ awọn Kerubu ti a fi wura ṣe. Nigba ti Jesu ku, aṣọ ikele naa faya lati oke de isalẹ, o si ṣi ọna silẹ fun gbogbo eniyan latti wọle. Eleyi n fi han pe anfaani irir fifi Ẹmi Mimọ wọ ni ṣI silẹ fun gbogbo eniyan. Ko si ẹni kan ti o ni iriri yi ṣaaju iku ati ajinde Jesu. Ki O to pada lọ, O ni o ṣe anfaani fun Oun lati lọ ki Olutunu (tabi Ẹmi Mimọ) ba le wa. Ileri Rẹ̀ ni pe Oun yoo fi Ẹmi Mimọ wọ wa, yoo si fun wa ni agbara lati ṣiṣẹ fun Ọlọrun.

**Igboya Nipasẹ Ẹjẹ Naa**

Nigba ti olori alufa ba lọ inu Ibi Mimọ Julọ ni Ọjọ Etutu, oun a maa mu ẹjẹ fun irubọ ẹṣẹ pẹlu rẹ̀. Jesu mu apẹẹrẹ ẹbọ ẹṣẹ yi ṣẹ, nigba ti o kú lẹyin bode Jerusalẹmu; pẹlu Ẹjẹ Rẹ̀ ti a fi bo ọkan wa nigba ti a sọ wa di mimọ, a le fi igboya beere lọwọ woli Majẹmu Laelae sọtẹlẹ nipa rẹ̀, ti awọn angẹli paapaa n fẹ lati wo. Eyi yi ni "Ọna titun ati ãye." Eyi ti Jesu ṣẹ funwa nipa iku Rẹ̀ lori agbelegbu ati ajinde Rẹ̀, ati lẹyin eyi nipa riran Olutunu.

**Lilọ si Ile-Isin**

Ro o wo bi ilana Ọlọrun fun igbala ti tobi to! O ṣẹ gbogbo eyi ti o wà nipa Rẹ̀ lati ṣe; ojuṣe wa ni i ṣe nisinsinyi lati ri i pe a de oju-ami. A ni lati di ohun ti Oluwa ṣe fun wa mu ṣinṣin, nitori pe a le sọ igbala wa nù nipa aibikita. Paulu kilọ fun wa pe  ko gbọdọ jafara nipa lilọ si ile-isin. A le jẹ iṣiri fun ara wa ninu igbagbọ bi a ti n pade lati sin Ọlọrun; awọn iwaasu a si maa kọ wa si i nipa ifẹ Ọlọrun. A gbọdọ maa gbadura ojoojumọ ni ile wa, ṣugbọn ohun iṣri ni pẹlu lati gbadura agbapọ ninu ile Ọlọrun.

**Ibinu Ti O Muna**

Bi eniyan ba pada sẹhin kuro ninu ohun ti o ti ni lẹẹkan, Ẹjẹ Jesu ki yoo tun bo o mọ;Ọlọrun si kilọ pe Oun yoo ran "idajọ ti o banilẹrù ati ti ibinu ti o muná". A ti kọ ẹkọ bi o ti jẹ pe ipa ti wa ninu eto irapada ti pọ ju ti awọn eniyan ti o wa labẹ Ofin Mose lọ; a si le da awwọn eniyan wọnyi lẹbi nigba naa bi a ba ri ẹlẹri meji lati tako wọn nigba ti wọn ba saigbọran. Ijiya naa paapaa le jẹ iku. Bi Ọlọrun ba fi ọwọ danindanin mu ọrọ Rẹ̀ bayi nigba aye Ofin Laelae, iru iya wo ni o tọ si ẹni naa ti o tun ṣẹ lẹyin ti Jesu ti fi Ẹjẹẹ Rẹ̀ wẹ ẹṣẹ oluwarẹ̀ kuro! "Ohun èru ni lati ṣubu si ọwọ́ Ọlọrun alãye" (Heberu 10:31). Ọõrun jẹ Ọlọrun ifẹ, O si ti ṣeleri pe "kò si ohun rere ti yio fà sẹhin lọwọ awọṅ ti nrìn dede" (Orin Dafidi 84:11). Ṣugbọn Ọlọrun idajọ ni Oun I ṣe pẹlu, yoo si ran idajọ sori ẹlẹṣẹ.

**Iṣura ni Ọrun**

Ọlọrun n ṣe akiyesi bi awọn eniyan Rẹ̀ ti ṣe n fi ara da inunibini ti o n de ba wọn. Paulu n sọ fun awọn ara Heberu ti i ṣe Onigbagbọ pe wọn ti fi ayọ gba ikolọ ẹ̀ru wọn. Wọn ko banujẹ pupọ bi wọn ba sọ ninu ohun ini wọn ti aye nu, nitori pe ni Ọrun awọn Onigbagbọ tootọ ni ọrọ ayereye -- iṣura ti ohunkohun ko le bajẹ.

A o san ere fun wa fun igbẹkẹle wa ati igbagbọ wa ninu Ọlọrun. Gbogbo awọn eniyan Ọlọrun ni yoo ni iyiiriwo ni aye yi, ṣugbọn bi a ba bori awọn iyiiriwo wọnyi, a o gba Ade ogo ti Ododo. Paulu gba awọn Onigbagbọ ni iyanju lati ni suuru, lati di igbagbọ wọn mu diẹ sii, ki wọn ma ṣe jẹ ki Satani mu wọṅ rẹwẹsi lẹba ọna.

Lẹyin eyi o tun pada lọ si iṣisẹ kinni ninu irin-ajo Onigbagbọ: "Olododo ni yio yè nipa igbagbọ" – ki i ṣe nipamimọ nkan lara. O ṣe e ṣe ki a ri ohun ti o le mu wa rẹwẹsi ki a si ni idaamu, ṣugbọn bi a badi igbagbọ wa mu ṣinṣin, Jesu yoo mu wa la a ja yoo si tun fun wa ni iranlọwọ ti yoo tun mu inu wa dun. Ẹ jẹ kia wi bi i  ti Paulu pe, awa ki yoo fa sẹhin. Awa jẹ iru awọn wọnni ti o n fẹ lati ni idaniloju pe ọkan wa yoo ye: nigba naa ni a le wa titi laelae ni Ọrun pẹlu Jesu.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ṣe ti Ọlọrun ko ni inu didun si irubọ awọn Ọmọ Israẹli ni akoko Isaiah?
2. Tani yoo "jẹ ire ilẹ na"?
3. Ki ni Jesu wi pe Oun wa si aye fun?
4. Awọn wo ni O pe ni iya Rẹ̀, arakunrn Rẹ̀, arabinrin Rẹ̀?
5. Nigba wo ni Jesu yoo mu idajọ wa sori ẹlẹṣẹ?
6. Tani yoo ṣe akoso aye ni igba Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun?
7. Bawo ni a ṣe le ni igboya lati wa iriri fifi ẹmi Mimọ wọ ni?
8. Ki ni Paulu sọ ninu ori iwe yi nipa lilọ si ile-isin?
9. Bawo ni olododo yoo ṣe yè